For Sale

3, Toner Bedford Lorry (Bolękaja) with all Particulars correct Available for inspection, at 37 Ojuelegba Road. Suru lere.

Phone, 12, Suru lere Or 21985. Lagos.

# ỊROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

Oja Gbanjo

Tete wa ra tirę ki o tetan Kerosine Stove titun to şeşe de. Iye owo rę tęlętęlę 35/-

Iye owo nisisiyi 30/-

Bere ni

ANJORIN Bros & Co
118, Griffith St, E. B.

Y. AROWOLO
The Manager

VOL. III No. 124 MONDAY NOVEMBER 16 — NOVEMBER 22 1959 KỌBỌ KAN (1d)

# Faranse so wipe Esin iwaju ni tehin nwo Sare

Faranse gba lehin opolopo ariyanjiyan pelu Ijoba Gesi wipe, ko baru, on gba lati da etu Oloro na du o.

Lori wipe, bi awọn Gęsi, Amęrika, ati Rọşia ba dawọ ętu oloro buruku yi duro lọdọ wọn, bakanna, nitoripe, ęşin iwaju nitęhin nwoṣa. Nitoripe ęnikan ko le ma wa aję, ki ęnikan si ma fi ęnu şewuya lasan

Agbọ wipe awọn alagbara meteta ti a darukọ nwọnyi şeleri pe awọn yio dawo ętu buruku yi duro ni yiyin lọdọ wọn Faranse na si gba lati da t rę duro ninu okun yan in Sahara.

Şugbọn Faranse fi ye wọn wipe, toju tiyę ni aparo fi nriran, on yio si ma sọ awọn alagbara mẹtẹta nwonyi, bi on ba ri eyiti o yọ kęlękęlę lo fi ọwọ ba ike on ko ni wi tęlę ki on totọ yin ti on ninu Sahara nitori pe ogun agbọtęlę ko npa aro

## Oye oba Ijebu fe da houhou sile

Ijębu-Ode. Agbọ Irohin pe ęniti afọbaję ni Ijębu-Ode yan lati ję oye Awujalę

WO OJU EWE KERIN

# Kotu ni ki ijo Satide Sunday lo kowe si Alase Idibo

ABA. Alaşę idibo ti o mbę nilu Eko, ti şe ikede wipe ni ọjọ Saturday 12th oşu December 1959, ni ao şe idibo jakejado ilę Naijiria si igbimọ nla ti Ijọba Apapọ şe, şugbọn ijọ Satide Sunday (Seventh day Adventist) sọ wipe gbọn awọn na lo ti daniyan lati dibo, bi nwọn ba fi ibo na si ọjọ Satide 12th ko ni le fun awọn laye lati dibo, nitoripe ọjọ isimi ni ọjọ na ję fun wọn, ayafi bi nwọn ba le yę ọjọ idibo na si ọjọ Friday 11th oşu December 1959.

Awọn ijọ na wa gbe ejọ na si kọtu ganran lo ba adajọ agba wipe ki o ba yę ọjọ idibo na si ọjọ Jimọh. Adajo na sọfun wọn wipe kotu ko lagbara lati yę ọjọ idibo nitoripe aşę rę ko si ni kọtu rara, ęniti aşę na wa lọwọ rę ni Alaşę idibo.

Ọgbęni R. E. Wraith tio ję alaga idibo sọ fun ọgbę ęni Ubani-Ukoma ti o ję aşoju fun ijọ Satide - Sunday pe awọn ko ni gba lati yę ọjọ idibo na si igbamiran fun ohunkohun. Nitotọ ni on ti gbọ wipe enia pupọ lo wa ninu ijọ yi ni ilu Aba, Ahoada ati Ijọ. Imọran ti on le mu

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tęlęrilọ lęyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

£45 Ni a nta Pęlu Enjinni Pętrol tabi ati pęlu Ẹlętiriki Mutọ.

O WA NI SỌBU:-

Akoshile Brothers,
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE ję ogun pa taki ta şe ni Aşepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ępolọpọ ọdun sęhin pęlu idaniloju fun Awọn Işę ribiribi ti o ti nşe. MOGBAYI BABY MIXTURE ję egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu ọmọde, jędi j ę d i Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan mitan bębę lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu ję irọ run fun awọn ọmọde, osi njęki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ęku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE ję egbogi ti ko şe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ę ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rę.

Igo kekere rę ję 2/6d Igo nla ję 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515
34, Docemo Street Lagos Phone 24247

# NIPA ISLAM

## ALUKURANI KIṢE IWE ATỌWỌDA

Lati ọwọ WOLI EKO

Afufa ẹjọwọ ẹla ye mi bi Alukurani awọn Imale ko tiṣe jẹ atọwọda, nitoripe emi rika ninu itan wipe lẹ bi ti Anabi Mọmọdu ku tan ni awọn ọmọ ẹhin rẹ gẹgẹ bi Abubaka ati Umaru ṣeṣe wa ṣe akojọ, atọpọ ati akọsilẹ rẹ ati wipe Zaid si ni oluko iwe rẹ

Nitotọ ni igbati Anabi wa ni aiye wọn ko ko Alukurani si paper, bi ko ṣe wipe wọn ha si ori.

Ṣugbọn iyẹn ko ja si wipe enia lo ṣe. Bi o ba mọ iru iwe ti Alukurani jẹ gidi, iwọ Woli yio mọ pe o ta yọ ohun ti ẹda enia le gbidanwo lati ṣe, gẹgẹ bi Ọlọrun papa tiṣe wi ni Kurani 2 ẹsẹ 23 ati 24.

Ekini ni wipe Alukurani sọ ọrọ lori gbogbo ẹkọ aiye patapata laiko fi ẹyọkan silẹ (History, Science, Law Economics Art, Technowlogy (etc) eyi ti ko si ẹda kan ṣoṣo ti o le kọ gbogbo rẹ papọ bi o ti wun ki o fun ni ẹbun ọpọlọ to ti o si fi gbogbo igbesi aiye rẹ kọ ẹkọ. Iyalẹnu Alukurani si tun wa de gongo, nigbati a ba ṣe iranti pe ẹniti a fi gbogbo nkan wọn yi si ni ẹnu ko de ile ẹkọ kankan ni rara yala ni kekere tabi agbalagba, ko mọ kikọ beni ko mọ kika (raw Illitrate)

Eyiti 'Woli' sọ pe awọn ọmọ ẹhin Anabi ṣe akojọ rẹ, o yẹ ki o le sọ fun wa ẹsin ti o sọ awọn ọrọ nwọnyi silẹ ki o to di pe awọn wa ri kojọ. Ohun kan na ti a le fi mọ bi iwe kan jẹ atowọda tabi ko jẹ bẹ ni Kurani na ti sọ ni ori 4 ẹsẹ 82 wipe bi o ba jẹ wipe ẹda miran lo ṣe sọ Kurani kalẹ ni, a ko ba ti ma ri ọpọlọpọ iyapa ninu rẹ.

Nitorina, laiko jẹ wipe Woli tọka si iru awọn iyipada, itakorawọn, ati isọkusọ ọrọ ninu Kurani gẹgẹbi eyiti awa ntọkasi ninu Bibeli wọn, ọrọ rẹ yi ko le ṣiṣe rara. Bi ọkan rẹ ko ba si gbagbọ wipe ọdọ Ọlọrun ni Kurani ti wa, jẹki on na pe awọn ẹlẹgbẹ rẹ nipa ijinlẹ ẹkọ, ki wọn si ṣe akojọ iru rẹ kan, nipa didungbọleti, yiyanju ni ọrọ, jijagara ni ododo, yiyanju ni ofin ati sise akotan ọrọ aiye. Koran 11 : 13, 10 : 38, 2; 23.

## ALO O! ALO

1. Ọna ti ọmọ araiye ko tọ, ti ero ọrun ko tọ, ọjọjumọ lo ndan o. 2. Oyinbo kọle ko loju o. 3. Kukute oju ona o ko Onde kọrun o. 4. Esinsin abẹ Iroko, ajọni ma fi ara han ni o. 5 Igbo gba Erin, o g'a Ẹfọn, ṣugbọn ko gba ọmọ Ajantala o. 6. Oku ku nile ọba Lailo, a gbe sinu Posi, o ni ki nwọn fi on silẹ pe on mọna Ọrun. 7. Oṣupa abẹ iti, aran ma dele ọlẹ. 8. Erin ku, magudu fijẹ. Ẹfọn ku magudu fijẹ, magudu ku kori ẹni ẹ on o

1. Ipako Ọpẹ 2. Ẹyin Adẹ 3. Ifi.pẹ 4. Ebi 5. Atẹ́fẹ 6. Okẹle Ẹba 7. Owo 8. Ipẹsan.


## Iwe Ilana Ifa, Erindinlogun, Iyanrin tite, Iwosan ati etutu sise pelu Egbogi Ajebidan

Ha! eti rẹ melo? Ogbokangi Babalwo ni o ṣeṣẹ se iwe yi fun tita ati fun anfani gbogbo enia, ohun ti o wa ninu iwe yi ni () Ayajọ ti o daju hanrann, (2) Yanrin tite, (3) Egbogi Ajẹbidan, (4) Eyọnu awọn agba (5) Awure wibe, jẹbẹ, (6) Etutu iwaṣẹ Ajẹbidan, (7) Ojulowo iwe Ifa ni iṣe. Babalawo tabi awọn ti o ba fẹ kọ Ifa nilati ni Iwe yi lọwọ, bi o ba ni iwe yi lọwọ, awọn Ọta, Ẹlẹiye, Alapeta, Apẹniapa, Adahunsẹ Ologun, Babalawo ati awọn enia majẹki tẹni sunwọn ko ni lagbara lori rẹ.

IYE OWO

10/6d ẹyọ kan, £3 mefa, £5 : 0/- Dọsini.

## Turari Ajebidan

Turari yi tun lagbara bakanna lori awọn Ẹlẹiye, nipa lilo rẹ, o ko ni tọ ita ọja, agbana ko si ni wọ inu igba rẹ, o le lo fun adura Tetedamilohun, Ako jalugbe ni fun awọn Emi okunkun, ni kukuru, Gbogbonse ni Turari yi, danwo

IYE O..O

10/6d Pangolo, 5/6d Idaji 3/- Idamẹrin 1/- Idarun

Iwe Itumọ Ala 2/6d, Gbedegbẹyọ Hausa 2/6d, Certificate of service 5/6d ẹyọ kan.

FI OWO RANSẸ SI:- J. O. SHOYINKA, 6, Ojo Road, Oduabore Mushin.


ÈTÒ ẸKỌ AWỌN ÀGBÀ



Eto ẹkọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe fun awọn agba, l'ọkunrin l'obirin, ti ko kọ ẹkọ tan ni ile-ẹkọ kekere tabi ti ketile ko rara, l'aye lati ṣe atunṣe nipa ẹkọ wọn. Ijọba nṣe iranlọwọ fun wọn lati le kà ati lati kọ iwe ni ede ti wọn ki nwọn bale ṣe ipa ti wọn daradara ninu iṣe ilesiwaju ti iṣelu ati ti igbadun awọn enia. Ijọba ti pese owo fun awọn oṣiṣẹ ti nmu ojuto eto ẹkọ yi fun tiṣẹ ati pinpin awọn iwe Yoruba ati ti ede oyinbo fun kika. Ijọba Ipinlẹ tun nfun awọn Ijọba Ibilẹ ni owo oṣu ti nwọn nsan fun awọn ti nṣe eto ẹkọ awọn agba ti Ọga Ile Iṣẹ eto ẹkọ ti fi aṣẹ si gbogbo wọn. Ijọba si nṣe iranlọwọ bakanna fun Ile Ika'we ni Ifeto ati fun iwe irohin nilẹ.

Owo ti Ijọba fi silẹ fun iṣẹ ẹkọ awọn agba ni ọdun 1955 si 1956 jẹ ẹdẹgbàfa poun, ti 1956 si 1957 jẹ ẹgbàwa poun o le ẹgbẹsan ati ogun. Iye kanna ni Ijọba na ninu ọdun 1957 si 1958.

Awọn ọdun mẹta ti o koja awọn agba ni l'ọruko silẹ fun ẹkọ yi jẹ ọkẹ marun o le ẹgbàwa ati ọdunrun o din mẹtadilogun—ni ọdun 1955, awọn ti nwọn fi oruko silẹ jẹ ẹdẹgbàfa ni ọdun 1956 ọkẹ meji abọ, ni ọdun 1957 ọkẹ meji o le ẹdẹgbẹjẹ o din mẹdogun.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Orun Nigiria l'ugbe ọrọ yi jade.

# ITUMO ALA awon onibere

DABIRI AJAO. IKEREKU VILLAGE ABEOKUTA

Aiye rẹ ti dara ninu ọdun yi, ọrọ rẹ wa ku ki o le fẹnu rẹ m'ẹnu, ki awọn ọmọ araiye ma ba da o ni agbo sina. Ko si ohun ti o le dawole lasiko yi ti ko ni bọ si rere.


# MA SO IRETI NU RARA O

Bere awọn ojulowo egbogi Jamani ati orişirişi ilu miran wọnyi pataki ni fun 'AJO' tabi 'ITỌJU' Obinrin tabi Ọkunrin, ti ọkọ ati iyawo ti o daju, Meji iru wọn ko si ni gbogbo şọbu ni igboro ilu Eko.



**Ekini:-** Egbogi ti a npe ni ERMELINDA fun Obinrin orişi mẹta lo wa ninu Pali re, o pa bambari fun ajo tabi idiwọ Adọta sile (50/-) ni owo pali kan ję, owo ọkọ 3/6

**Ekeji:-** Egbogi ti a npe ni SANURSEX fun Obinrin Silemejilelọgbọn pelu sisi (32/6d) owo ọkọ 2/6

**Ẹkẹta:-** Egbogi ti a npe OPO-JUVENCE fun obinrin. (ojulowo Egbogi awọn Faranse Şilemejidinlogun abọ (18/6 owo ọkọ 3/6

**Ẹkẹrin** Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN fun obinrin. Silemẹrinla-abọ 14/6 owo ọkọ 2/-

**Ẹkarun:-** Egbogi ti a npe ni FANDORINE fun obinrin (Egbogi Faranse) Silemẹrila-abọ (14/6) owo-ọkọ 2/-

**Ẹkẹfa:-** Egbogi ti a npe ni OSTORPIROS fun obinrin Silemẹjọ-abọ (8/6) owo ọkọ sileken pere (1-).

## Ojulowo Egbogi fun AJo Ilera ti Okunrin

Ekini:- Egbogi ti a npe ni SANURSEX
Ọgbọn şile (30/-) Igo nla Owo ọkọ 3/-

Ekeji:- Egbogi ti a npe ni TESTONIC
Pọwun-kan (£1) igo kekere mẹwa-abọ owo ọkọ 2/-

Ẹkẹta:- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN
Silemejila-abọ (12/6) owo ọkọ 2/-

Awọn egbogi wọnyi lagbara gidigidi wọn si nşişẹ ribiribi fun awọn ti wọn nlo wọn pẹlu, wọn ko dabi awọn egbogi Robirobi ti wọn nta kakiri igboro işẹ wọn yatọ patapata, o si daju pẹlu.

**Bere** ojulowo Egbogi omiran fun orişirişi amodi ti o ba fẹ ni şọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, PalmChurch Street P. O Box 333**
**Lagos Nigeria Phone 22878**

**Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-**

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE. IBADAN.

ati ni Abimbola Medicine Stores
B29 Okesha Street Ilesha

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe şọbu ti wọn nta lo gbe ranşẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi orişi omiran funo o, maşe gba rara.


# "Eto nipa Itesiwaju Igbeyawo ni ilu Omupo"

Moki gbogbo ẹnyin Ọmọ Omupo ti o wa li Eko ni Ibadan li Omupo tabi ni ilu Ibomiran, lọkunrin tabi lobinrin lọmọde tabi lagba ni Wundia tabi Adelebo, lati fi si etigbọ nyin akoko ti to lati ma losi Ile tişe Ilu Omupo fun iyawo gbigbe.

Bakanna si tun ni akede si awọn idile Ọkọ tabi idile Iyawo lati ma jafara lati fa ọmọ wọn fun Ọkọ lasiko, bẹna sini fun awọn Ọkọ lati ma san şokoto wọn giri lati şe eto tio batọ ati eyi tio bayẹ fun idile Iyawo won ki asiko na to ju. Asi kede si awọn iyawo na ki wọn maşe gba agbatalẹ ju gẹgẹbi awọn ẹgbẹ Ọmọ Ilọsiwaju Ọmọ Omupo tişe eto lati ẹhin walọ.

Mose ikede yi si gbogbo ọmọ Omupo li gbogbo agbaiye pe gẹgẹbi eto ti Ẹgbẹ Ilọsiwaju ọmọ Omupo şe nipa Igbeyawo eyiti gbogbo Ilu si ti gba ti wọn siti ngşebẹ lati Ọdun 1958. Lekansi mokede si gbogbo ọmọ Omupo li gbogbo agbaiye wipe lati ọjọ ti Irohin yi ba ti jade lọkunrin tabi lobinrin lọmọde tabi lagba ki wọn di amure ara wọn, ki wọn si bẹrẹsi losi Ile ti şe Ilu Omupo lati al ọjọ na ati pe Iyawo gbigbe na yio pari ni oşu kini Ọdun 1960. (1st January 1960)

Fun ẹtigbọ nyin, ẹnikẹni lọkunrin tabi lobinrin lọmọde tabi lagba ni idile Ọko tabi ni idile Iyawo tio ba şori kunkun tabi tio ba tapa si ofin ti Ẹgbẹ Ọmọ Ilọsiwaju Ọmọ Omupo tişe, laişe aniani oluwarẹ yio jiya gẹgẹbi eto ẹda iwe na ti a tẹka fun nyin ni Ile Ẹgbẹ tişe Glover Memorial Hall li Eko ni ọdun 1958.

Ọkọ Ọba koni şawa lẹsẹ o, Amin.

KI ỌLỌRUN ỌBA KIO ŞE AWỌN IYAWO NA LI ABIYAMO. AMIN.

Emi ni Sunday Abaraham Ezekiel
29, Oke-Olowogbowo Street,
Lagos - Nigeria. 9th November, 1959.

# Ipade keji awon egbe I. C. F. T. U.

Ipade awọn ẹgbẹ oşişẹ T. U. C. bẹrẹ nilu Eko lọjọ Monday ọsẹ to kọja, nwọn yan awọn ẹgbẹ marun lati mogiri si işẹ ẹgbẹ. Ekini ninu ẹgbẹ na ni awọn ti yio ma wa ilọsiwaju ẹgbẹ T. U. C. Ekeji awọn ẹgbẹ ti yio ma jẹri wọn.

Ẹkẹta ni awọn ẹgbẹ ti yio ma tọ wọn si ọna. Ẹkẹrin ni awọn ẹgbẹ ti yio maşetọju owo. Ẹkarun ni awọn ti yio ma mojuto işelu.

Ẹniti o se Alaga lọjọna ni Ọgbẹni Tom Mboya, o sọ wipe o jẹ ohun ẹdun fun on pupọ nitori ti awọn ẹgbẹ T. U. C. tilẹ Ghana ko le wa si ipade na, ohun ti o fa sababi ti ko jẹki ẹgbẹ tilẹ Ghana le wa, ko nşe ohun ti akole tunşe.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa sibẹ ni Ọgbẹni H. P. Adebọla, S. I. Ese, L. L. Borha, J. B. Galadima, A. Adeleke, J. Ijẹh, M. Odina, ati E. Okonkwo.

# OWE ILE YORUBA

(1) Eniti a fi ori rẹ fọ agbọn ki jẹ ninu rẹ (2) Owumi ki a jerae pẹ lẹnu, ofa ni ko jẹ. (3) Ogẹdẹ to bọ somi ti o şe taloo, abuku ara rẹ ni. (4) Bo ba di ti kankan, opolo ga diẹ ju Amnrin, Amurin na si tun ga diẹ ju ilẹ lo. (5) Ninu olokiti, baba lọbọ (6) Ọmọ oloko to ni on ko yo, ọwọ jwa rẹ ni (7) Ẹniti a ba fẹhinti kaunu didun ọsan, kikan lo nfẹ fun ni mu. (8) Aguda koje ninu ọkọ gesi, onikaluku gbọkọ tirẹ lo ni. (9) Alaru to ni ki aje şe on pa, kini kẹlẹru wi. (10) Ana to roju, ọmọ rẹ lo ma gba (11) Obi ko si mọ ajogbe lo ku. (12) Ko jẹ ki oti ẹni di, koni jẹki inu ẹni dun (1) Asọrọ kẹlẹ bojuwo igbọ, igbẹ kiro, ẹni a sọ fun lo ma nro ni kiri.

# OJU RERE KI NPANI O SI TUN NPANI

## Lati owo J. A. Ade Iludun

Baba Agbẹ kan lọ si oko bi osi ti de oko ti o wo iwaju osiri ejo kan ti nsare bọwa ni ọkankan Ibi ti agbẹ yi wa. Nigbana ni agbẹ yi gbiyanju lati sa asala fun ẹmi rẹ ni ejo yi ba pe baba agbẹ na pe ki o maṣe salọ. Ejo na sọ fun baba pe Aṣa lo nle on bọ lati pa on jẹ, ki agbẹ yi gba on ki aṣa na maṣe pa on jẹ, ni Ejo ba duro ro ẹjọ fun baba, baba na si duro lati ṣe igbala fun, baba na sọ fun pe ki o jẹki wọn lọ si abule on, Ejo na sọ fun baba pe abule na ko le gba on, nitoripe Aṣa le mu on nibẹ.

Agbẹ sọ fun pe ki o wa ko sinu apoti on Ejo tun ni asa yio ri on ninu apoti na. Agbẹ na ni ki Ejo na wa kosi agbe on, on yio di agbe na pa dada. Ejo ni yio tun ri on nibe nigbana ni agbẹ na bere pe Ibo ni ki on wa fi pamọsi Ejo yi yi dahun pe ki agbẹ yi jẹki on kosi ẹnu rẹ pe ti asa ba lọ tan on yio si sọkalẹ osi bẹ dada pe kio jọ wo

Nigbana ni agbẹ ba gba fun ko pẹ pupọ ti ejo yi kosi ẹnu baba yi nigbati asa de, asa na si bere lọwọ agbẹ na pe ibo ni ejo yẹn ṣagba agbẹ si dahun pe on ko mọ ibiti ejo salọ nigbana ni ẹiyẹ asa ba pẹhinda lo ba lọ. Lẹhinna ni Baba ejo pe kio ṣọkalẹ asa ti lọ o nigbana ni ejo badahun pe ibo ni kio nsọkalẹ si. Nitori Ibi ti on wa yi oti tẹ on lọrun nitori ẹde wa nibẹ on kosi se wahala lati jẹun Ire si wa pẹlu atipe kosi on ti on fẹ jẹ ti kosi ninu torina on kole sọkale mọ o.

Agbẹ na si lẹ sọ fun ba pupọ ṣugbọn o kọlati kalẹ Eleyi ba agbẹ ninu jẹ pupọ osi bẹrẹ si ṣọkun. Ibẹ ni ẹiyẹ akala nrekọja lọ lo ba bere lọwọ Baba agbẹ yi pe kini npa ẹ lẹkun.?

Nigbana ni baba agbẹ yi ba kẹjọ lo ba ro fun ẹiyẹ akala, ẹiyẹ akala na ba bere ẹjọ lọwọ Ejo ki o ro fun on niwọn iba diẹ. Ni Ejo ba ro ẹjọ, ẹiyẹ akala si dahun pe ki Ejo rna yọ oju sita diẹ ki on ri nitori oju ni ọrọ wa, bi Ejo ti yọju sita lati ro ẹjọ ni ẹiyẹ akala ba ṣa ni iko, lo ba wọ lulẹ nigbana ni Baba bayọ ada lati pa ejo yi, ṣugbọn akala ne ni ada ba, ni ẹiyẹ akala na ba ku.

Ẹko ri mọ wipe oju rere ama pani, asima ko ba enia.

Olọtu modupẹ aiye ti e gba mi. ọkọ ọba ko ni sa yin lẹsẹ o. Ajinde ara yio majẹ, Odigbose o.!

---

# Egbogi fun tita ati Iwosan Orisirisi

(1) A nṣe orisirisi ojulowo Egogi loke petesi yi fun tita ati fun Itoju orisirisi Aisan tabi Amodi (2) A nṣe Itoju obinrin titi wọn yio fi loyun D. V. (3) A nṣe Itoju aboyun titi wọn yio fi bimọ D. V. (4) A nṣe Itoju Obinrin ti nkan osu se mọ lara (5) A nṣe Ajo fun t'ọkunrin t'obinrin ki wọn leri iṣẹ ṣe.
(6) A nṣe Ajo fun obinrin kio le ri ọkọ fẹ. (7) A nṣe Ajo Okunrin ki o le ri aya fẹ. (8) A nṣe Ajo fun onisowo ki won le ma ri oja ra, ati ki wọn le ma ta daradara
(9) A nṣe Ajo ki irẹpọ wa larin t'ọkọ t'aya. (10) A nṣe Ajo ki aranse le bani kale san gbese taba jẹ (11) A nṣe Ajo fun iṣẹgun lori nkan ajijodu tabi ọta ati Ejọ Court. (12) A nṣe Ajo oju didun. (13) A nṣe Ajo fun Adakole pẹlu imarale Aleko ọkunrin
(14) A nṣe Ajo fun Eyọnu, Aiye Ẹnọnu awọn iya wa (15) A nṣe Ink fun kikọ Petition (16) A nṣe egbogi Isoye ati onmọ kale Bori tai (Pass) orisirisi Idanwo (Examination)
17. Turare Arisiki, Lojojumo (fun Itaja Iraja, osiu nle Alujonu buburu kuro oila) Cigarette Cup or Pkt. 10/- 5/- 2/6

J. B. Crownson Odujọbi
Top Floor, 16, Bamgbose Street,
LAGOS NIGERI
P H O N E 24318.

Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone: 21986. Olotu E. A. Adeniji 51 Tẹjuoṣho Street Suru Lere YABA

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN
EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)

---

# E ma polowo Ojayin sinu Iwe Irohin Imole

---

### O PERE LATI OJU EWE KINI

wa niyi wipe, ọjọ Satide kuru jọjọ, ile ko osu ki ọjọ Satide to wọ. Ọmọ tio Satide—Sunday ti o ba fẹ dibo le ṣe bẹ bi nwọn ba fẹ dibo ki o to di pe ile su.

### OBERE LATI OJU EWE KINI

Ọba Ijẹbu-Ode ni ọmọ kunrin kan ti oruko rẹ njẹ Sikiru Adetọna,

Lori ẹniyi ni Ọgbẹni tise Emmanuel Ọjalẹyẹ ti ọja Akọwe fun idile Anikrlaya kọwe, ti o si tako wipe awọn Afọbaiẹ siṣe ni yiyan ẹniyi sori oye ọba

Ẹniti ko baiti ni iyawo abi ti koiti bimọ ti ọdun orirẹ koiti pe merinlelogun koiti ni ẹtọ si oye Ọba Ijebu, oni ki wọn ranti pe ni ọdun 1929 irurẹ ti ṣẹlẹ ri.

---

# Aburo Oba Geesi niyi



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ọmọba Margaret ti a jẹ aburo ọba Gesi, nigbati o lọ se asoju fun Elizabeth Iya Ọba Gẹsi ninu afin Saint James nilu Londọnu. Awon eui pataki ti o pe ipade na ni awọn ọmọ ogun ori ilẹ (Soldiers) awọn ọmọ ogun oju omi (Sailors) ati awọn ọmọ ogun oju Sanma (Airmen) Iya oba lo ni ipo alaga ojo na, sugbon [illegible] kekere kan nyọ ọ lẹnu.